OBA OLOBU PE OLU ILARO LEJO LORI OYE BALE


# IROHIN YORUBA

Ęsin Oro Wa— "IWAJU L'ỌPA ĘBITI NRE SI"


**Akiyesi**

A fę kawọn onibara wa ma san owo si apo wa dede, ẹniti ko ba san owo tirę, ki o ma ya a l'ẹnu bi a ba da a duro lojiji, ao si gba owo wa lọwọ rę.

*OLOOTU,*
Irohin Yoruba.


VOL. IV NO. 639 IBADAN, MONDAY, NOVEMBER 13, 1950, OWO IWE IROHIN YORUBA — KOBO KAN (1d)


ADAJO TU EJỌ IGA IDUNGANRAN KA : ỌLỌLA GERARD HOWE DI ADAJỌ AGBA

## Obinrin Kan Ja Si Kanga O Si Ku

ILỌRIN—Ni aro ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu kẹje ọdun yi ni ariwo nla ta wipe Iyaafin Adunọla Ogbomọṣọ ti iṣe Iyawo Corporal Emmanuel Oyegbile yọ sinu kanga o si ku.

Bi obinrin yi ti ji ni aro ọjọ yi ti o si wa si ago-ọlọpa ni ọdọ ọkọ rę ti o si ba tan ile iṣe tan, ni o ba da gbere pe on nlọ wo awọn Baba ati Iya on ni adugbo Pakata ki on si pada. Ni ọkọ rę ba sọ fun u pe o dara o, ki o mọ pe o, ni o ba lọ.

Nigbati o de ọhun o ba iya rę fọ aṣọ tan, ni o ba pe ki on san ęsę ki on to ma a lọ. Bi o ti fę bu omi ni ęwę rę ba yọ sinu kanga, nigbati iya rę ko tete ri i ko wọ ọdẹ ni o ba tun lọ wo o ni ibi ti o ti nfọ aṣọ.

Gele rę ti iya rę ri ni oju omi ni o fi mọ pe ọmọ on ti ja si kanga. Ni awọn ba ranṣę lọ pe ọkọ rę, ẹniti o ti wa ninu ero pe pipę ti iyawo rę pę boya o nro ejọ ija wẹwẹ kan fun iya rę ni. Ati igbati o de ọhun, ti o ba gbogbo wọn pelu ẹkun asunwa.

Ki Oluwa tu ọkọ obinrin na ati gbogbo awọn enia rę ninu o, ki Oluwa fi iku rere pa gbogbo wa o—amin.

### IYAWO A TỌWỌ BOSUN, BOLUWAFẸ

EKO—Ni ọjọ Aiku ti nṣe ọjọ karun oṣu yi ni a gbe Omidan Fatilatu ni iyawo fun Ogbẹni Karimu Yesufa, a si ṣe igbe-awo na ni ọna ti Musulumi ni 3, Carr Lane, Eko. Ogbẹni Yesufa yi jẹ ọkan ninu awọn oṣiṣẹ "Daily Service."

Wa wo bi ọkọ iyawo ti fi ile pọn ọti ti o si fi ọna roka, eni se, ẹjẹti ati amuti ni nwọn fi ọti ati onjẹ ṣe ni ọjọ yi, ti awọn ore ọkọ ati awọn ẹbi ọkọ si nnawo bi ẹlẹda ti nwọn si njo bi kokoro ni ọjọ yi.

Diẹ ninu awọn ti o wa si ibi iyawo na ni Ọgbẹni Y. Ayinla Disu, B. L. Akibiyi, R. A. Lawal Olowo, G. A. Aigoro, J. Adebiyi, S. O. Akiọla, M. A. Bajorun, W. A, Babs Stowe, R. A. Subair, L. Ọla Bamgbose, A. S. Abiọlaji, S. Sadiku, S. O. Johnson gbogbo awọnwọnyi ni oṣiṣẹ "Daily Service" W. Olusesi, Y. K. Bamgbose, O. Ọla. Mati, M. Odunewu, A. G. Ọla Musa, Bashiru Thani, Tesilimi Wahabi, E. A. Sanyaolu ati awọn ti aye ko si lati da oruko wọn.



ỌBA ALAIYELUWA ADELE KEJI

## Adajo Tu Ejọ Iga Ka

Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni awọn pade ejọ Iga Idunganran nipa ape-le ejọ ti awọn Ọmọ-Ọba Dosunmu pe, pe ki Ọba Adele II o jade ni Iga ki Ijọ a mu kọkọrọ dani titi awọn a fi pari ejọ na tan patapata, ati pe ki Ọmọ-Ọba Adeyinka Oyekan ma a ba ejọ na lọ dipo Ọmọ-Ọba Tenalyemi Dosunmu ti o ku.

Nigbati awọn bere ẹjọ na ni iwaju Adajọ Agba Ọgbẹni S. B. Rhodes, awọn ko ri Ogbẹni Adeleke Adedoyin ti iṣe Agbẹjọro awọn Ọmọ-Ọba Dosunmu, Loya T. O S. Benson ni o wa ni kotu "Kotemilorun" (West African Court of Appeal) awọn fi ẹrọ isọrọ (Phone) bere nibẹ awọn ko ri.

Lẹhin na ni Adajọ ba sọ pe on ko tun le ye ejọ ejọ na mọ, nitorina on tu ejọ na ka, o si ni ki awọn Ọmọ-Ọba Dosunmu o lọ san pọnun mẹdọgbọn sile mẹdọgbọn (£26:5s) owo irinaẹ fun Ọba Adele keji.

### IMỌLẸ KRISTI MỌLẸ SI ILẸ KEFERI

IGANDO—Ni ọjọ keje oṣu kẹwa ọdun yi ni Ọlọrun ti ọwọ awọn ojiṣẹ Ọlọrun Ijọ Saviour Apostolic ṣe iṣẹ iyanu ni ilu yi lati sọ ọpọlọpọ ara ibọ ti nwọn nsẹ ẹlẹsin Mọmọdu di ọmọ igbala nipa ẹsin Kristi.

Diẹ ninu awọn Ogunlọgọ ti o gba Baptisimu ni ọjọ na niwọnyi: Mukandasi di Michael Ọduntan, Yakubu di Jacob Ọduntan, Lamisa di Gabriel Saka, Sanmọla di Isaiah Aṣọjo, Buariya di Emmanuel Salisu, Tẹsi di Joseph Ajayi, Yaya di Lawrence Suberu, Munirụ di Peteru, Mọrinata di Ruth Saka, Ayinatu di Hannah Ọduntan, Rabiatu di Lydia Ajayi, Simbatu di Maria Rabiu, Abibatu di Alice Raji, Osenatu di Sabinah Aṣọjo Mọriaatu di Sarah Suberu, Abẹni di Victoria Suberu, ati Phebean Ọduntan.

Awọn Alufa J. A. Ogundipẹ ati J. A. Ewetumọ, ni awọn ṣe


(Wo oju ewe kerin)


## Gerard Howe Di Adajo

Ọgbẹni Ọlọla Gerard Howe ti iṣe Aṣofin Ijọba (Attorney General) Nigeria ni Ijọba kede rę fun gbogbo enia gbọ pe Ọba Alaiyeluwa George kẹfa ti Ilẹ Oyinbo ti fi aṣẹ si igbega ipo ise rę pe ki o lọ ṣe Adajọ Agba (Chief Justice) ilu Hong Kong, lati rọ ipo Ọlọla Leslie Gibson.

Ọgbẹni Ọlọla Gerard Howe ko si pe ni Nigeria mọ ti o ba pada de ti yio fi lọ bere iṣe Adajọ Agba na ni ilu Hong Kong.

### ENI ỌMỌ SIN LỌ BIMỌ, ỌMỌ LA YỌ LE

AKINMỌRIN-ỌYỌ—Ireḥin ko to afojubi ni ere ọjọ yi jẹ, ni ọjọ kefa oṣu to kọja yi. Ni dede agogo mẹta ni awọn ọmọloku ti fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo enia lọrun, ki Edumare fi ọmọ rere gbẹhin awa na o—amin.

Lẹhin na ni Ọgbẹni Nasiru Dosu Faaji bere si fi ahu-bi-ẹkun rę ṣe idaraya fun gbogbo wa, awọn ọmọloku si bere si nawo bi ẹlẹda ni ọjọ na.

Ala ki awọn ọmọloku awọn bi Ogbẹni Ọdẹniyi Ajao, Ọlarogba Ajao, Segilola ati Afọlabi. Ẹbin Baba ayin yio dara.

## Ọba Olobu Pe Olu Ilaro Le'jọ

IBADAN—Ni ọjọ Aje ti iṣe ogbọnjọ oṣu ti o kọja yi ni Adajọ kotu nla Ibadan to o gbọ idi inkan ti Ọba Adebowale, Olobu Ilobu fi pe Olu Ilaro ni ejọ, lẹhin ti o gbọ ọ tan ni o ba fi ọwọ si ipejọ na.

Inkan ti Ọba Olobu pe Olu Ilaro ni ejọ si ni pe gẹgẹbi eto iṣedalẹ ilu Ajilete, Olu Ilaro ko ni aṣẹ lati fi enia jẹ oye Balẹ ilu Ajilete tabi ki o yan ẹnikan pe on ni oye Balẹ Ajilete tẹ si fun Ijọba lati fọwọ si i.

O si tun nfẹ ki Ijọba pa a laṣẹ fun u pe ki Olu Ilaro yọ ọwọ rę ati ti awọn aṣoju rę tabi ti awọn iranṣẹ rę kuro ninu ọran oye Balẹ Ajilete tabi lati tọka ẹnikan fun Ijọba pe on ni oye Balẹ Ajilete tọ ti ọe ki Ijọba fọwọ si i.

Ọgbẹni Loya Adesẹgun Ọdunbaku ni Agbẹjọro Ọba Olobu, Ọgbẹni Loya Ọbafẹmi Awolọwọ si ni Agbẹjọro Olu Ilaro, bi awọn ba ti pari ọran na ni ẹ o ma a gbọ.

OWE : TI A KO BA YỌ IPIN LIJOJU KA FI HAN OJU, OJU KI I MỌ PE ON NṢE ỌBUN

